Massachusetts Bay Transportation Authority

# BÍ A ṢE ŃWỌ ỌKỌ̀ MBTA
## Àwọn Ohun Ìpìlẹ̀

## ÌRÀNLỌ́WỌ́ NÍPA ÈDÈ

Àwọn aṣojú Àtìléyìn fún Oníbàárà MBTA ńsọ èdè Gẹ̀ẹ́sì àti Spáníìṣì, àwọn ògbùfọ̀ sì wà ní àwọn èdè 160. Àwọn ọlọ́pàá Inú ọkọ̀ MBTA àti àwọn Àṣojú Inú ọkọ̀ ní àwọn ibùdókọ̀ lè ṣe ìrànlọ́wọ́ fúnni láti lè jẹ ànfàní iṣẹ́ yìí.

Fún ìrànlọ́wọ́, pe: **Fóònù: 617-222-3200**
**Pípè Lọ́fẹ̀ẹ́: 800-392-6100**
**TTY: 617-222-5146**

**MBTA.com/language-services**

## KÍKÓPA NÍNÚ RẸ̀

Ìlọ́wọ́si àwọn ará ìlú jẹ́ ìpín pàtàkì kan lára mímú àwọn iṣẹ́ gbèrú sí i àti ní ṣíṣe ìpinnu, àwa sì má a ńgba àwọn ará ìlú níyànjú láti wá sí àwọn ìpàdé gbogbogbò MBTA láti lè sọ èrò wọn nípa àwọn iṣẹ́ wa. Àwọn àkíyèsí nípa ìpàdé ni a má a ńfi sórí ojú-ìwé àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ wa lórí ayélujára, ó sì ní àlàyé lórí bí a ṣe ńbéèrè ààyè sí àwọn ibùgbé àti ìrànlọ́wọ́ nípa èdè lọ́fẹ̀ẹ́ nínú.

**MBTA.com/events**

## ÈLÓ NI YÓÒ NÁ NI?

**Lílọ pẹ̀lú Ọkọ̀ abẹ́lẹ̀ lẹ́ẹ̀kan:**
$2.40 pẹ̀lú owó, KáàdìCharlie, tàbí Tíkẹ̀ẹ̀tìCharlie
**Lílọ pẹ̀lú Ọkọ̀ Agbègbè lẹ́ẹ̀kan:**
$1.70 pẹ̀lú owó, KáàdìCharlie, tàbí Tíkẹ̀ẹ̀tìCharlie
**Lílọ ní Ojú-irin Akérò lẹ́ẹ̀kan:**
$2.40–$13.25, èyí dá lórí bí ibití iwọ ńlọ ṣe jìnnà sí
**Lílọ pẹ̀lú ọkọ̀ ojú omi lẹ́ẹ̀kan:**
$3.70–$9.75, èyí dá lórí ibití o tí ńbọ̀ àti bití ò ńlọ
**Lílọbíbọ̀ ọkọ̀ tí ó jẹ́ àkànṣe:**
$3.35–$5.60, owó lílọ lẹ́ẹ̀kan fún oníbàárà kan

**MBTA.com/fares**

## OWÓ ỌKỌ̀ TÍ A TI DÍNKÙ

Àwọn akẹ́kọ̀ọ́ tí ó yẹ lè gba àwọn KáàdìCharlie ti Akẹ́kọ̀ọ́ (tí ó wúlò títí di ọjọ́ kọkànlélọ́gbọ̀n (31) Oṣù kejọ lọ́dọọdún) láti ọwọ́ àwọn ilé-ìwé tí ó ńkópa.

Àwọn ọ̀dọ́ tí ńgba owó tó kéré, tí ọjọ́-orí wọn jẹ́ méjìdínlógún sí márùndínlọ́gbọ̀n (18-25), láti ìlú kan tí ó ńkópa tàbí láti ààrín ìlú lè yẹ fún KáàdìCharlie Ìgbaniwọlé fún Ọ̀dọ́.

Àwọn tí kò ríran tàbí àwọn ènìyàn tí wọ́n ní àléébù ojú àti àwọn atọ́nà wọn lè wọ ọkọ̀ MBTA lọ́fẹ̀ẹ́ pẹ̀lú KáàdìCharlie Wíwọlé Aláìríran.

Àwọn àgbàlagbà (tí ọjọ́-orí wọn jẹ́ 65+) àti àwọn ènìyàn tí wọ́n ní àwọn àléébù ní ẹ̀tọ́ sí ẹ̀dínwó owó ọkọ̀ pẹ̀lú Ìwé ìgbaniwọlé Ọkọ̀ [Transportation Access Pass (TAP)].

**MBTA.com/fares/reduced**

## ÀWỌN ÀṢÀYÀN SÍSANWÓ MÌÍRÀN

Àwọn ọmọdé tí ọjọ́-orí wọn jẹ́ mọ́kànlá (11) àti kéré jù bẹ́ẹ̀ lọ, tí wọ́n wà pẹ̀lú oníbàárà kan tí ó ńsanwó yóò wọ ọkọ̀ lọ́fẹ̀ẹ́. A kò gbani láàyè ju ọmọ méjì lọ fún oníbàárà kọ̀ọ̀kan.

Àwọn ilé-iṣẹ́ lè kópa nínú ètò KáàdìCharlie àjùmọ̀ṣe, èyítí ó ńpèsè àwọn ànfàní owó-orí fún àwọn tí a gbà síṣẹ́.

**MBTA.com/pass-program**

## ÀWỌN WÁKÀTÍ IṢẸ́

Iṣẹ́ púpọ̀ nínú àwọn ọkọ̀-akérò àti ọkọ̀ ojú-irin a má a bẹ̀rẹ̀ ní aago márùn-ún ààrọ̀ (5 AM), a sì má a parí ní aago kan ààrọ̀ (1 AM), àwọn iṣẹ́ ọkọ̀-akérò kan ní àwọn ọ̀nà tí èrò ti má a ńpọ̀ a sì má a bẹ̀rẹ̀ ní bíi aago mẹ́ta ààbọ̀ ààrọ̀ (3:30 AM). Ìlànà ètò lílọ-bíbọ̀ dá lórí oríṣi ọkọ̀ àti ọjọ́ tí ó jẹ́ lọ́sẹ̀. Iṣẹ́ náà a má a wáyé púpọ̀ síi ní àwọn àkókò tí ọ̀pọ̀ ènìyàn ńkánjú wọ ọkọ̀ ní àwọn ọjọ́ kan láàárín ọ̀sẹ̀ (7 –9 AM àti 4 –6:30 PM) ju ní àwọn ìgbà mìíràn lọ. Iṣẹ́ ní àwọn Ọ̀nà tí Ọkọ̀-abẹ́lẹ̀ àti Ọkọ̀-akérò ńgbà (gẹ́gẹ́ bíi Ọ̀nà 28, 111, 116, àti òmíràn) ni ó wọ́pọ̀ jùlọ, wọn a sì má a ṣiṣẹ́ ní ìṣẹ́jú mẹ́wàá-mẹ́wàá sí mẹ́ẹ̀dógún-mẹ́ẹ̀dógún (10–15) tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ.

**MBTA.com/schedules**

## ÀWỌN ÌTANILÓLOBÓ NÍPA IṢẸ́

Nígbàmíì àwọn ìdìwọ́ má a ńṣẹlẹ̀ àti nígbàtí wọ́n bá ṣẹlẹ̀, MBTA a má a ṣàgbékalẹ̀ àwọn ààmì ìkìlọ̀ tàbí kí wọn pèsè àwọn òṣìṣẹ́ tí yóò ran àwọn oníbàárà lọ́wọ́. Àwọn iṣẹ́ ìtanilólobó lọ́wọ́lọ́wọ́ àti tí a ti ṣètò wà lórí òpó ayélujára wa. Àwọn èrò tún lè forúkọsílẹ̀ fún Àwọn ìtanilólobó-T láti gba àwọn ìtanilólobó àtẹ̀jíṣẹ́ tàbí imeeli.

**MBTA.com/alerts**

## ÌRÁÀYÈSÍI

Gbogbo àwọn ọkọ̀ akérò MBTA jẹ́ èyítí ó ṣeé wọ̀ fún àwọn ènìyàn tí ó ní àwọn àléébù ara, bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́ náà sì ni ọ̀pọ̀ àwọn ibùdókọ̀ abẹ́lẹ̀ àti ti oju-irin akérò. Àwọn ọkọ̀ ojú-omi àti àwọn ibi ìdúró ọkọ̀ ojú-omi jẹ́ èyítí ènìyàn lè ráàyèsí, ṣùgbọ́n wọ́n lè ní ìdíwọ́ fún ìgbà díẹ̀ látàrí lílọ sókè àbí lílọ sílẹ̀ ṣíṣàn ẹ̀kún omi.

**MBTA.com/accessibility**

The RIDE: The RIDE jẹ́ iṣẹ́ ojúlé-sójúlé ọkọ̀ MBTA fún àwọn abarapá. Bí o bá ní àléébu ara kan, èyítí ó ńdí ọ lọ́wọ́ láti lo ọkọ̀ akérò, ọkọ̀ abẹ́lẹ̀ tàbí kẹ̀kẹ́ ìkẹ́rùsí MBTA ní àwọn àkókò kan tàbí ní gbogbo ìgbà, ó ṣeéṣe kí The RIDE lè ṣe ìrànlọ́wọ́ fún ọ nípa àwọn àìní rẹ fún wíwọ ọkọ̀ akérò gbogbogbò.

**MBTA.com/accessibility/the-ride**

Àwọn èrò ọkọ̀ lè ráàyèsí àlàyé nípa ìdaṣésílẹ̀ àwọn ohun-èlò agbénigòkè lójú ẹsẹ̀ nípa pípé 617-222-2828.

## KÍKÀNSÍ MBTA

Àwọn èrò ọkọ̀ lè kàn sí MBTA ní ónírúurú àwọn ọ̀nà, bíi fóònù, imeeli, àti títẹ̀lé àwọn òpó ìdọ́ọ̀rẹ́ wa:

**Fóònù:** 617-222-3200
**Pípè Lọ́fẹ̀ẹ́:** 800-392-6100
**TTY:** 617-222-5146
**Imeeli:** MBTA.com/customer-support

twitter.com/mbta
facebook.com/TheMBTA/
instagram.com/thembta/
youtube.com/mbtagm
tiktok.com/@thembta
linkedin.com/company/mbta

## BÍ ÌṢẸ̀LẸ̀ PÁJÁWÌRÌ BÁ WÁYÉ

Gbogbo òṣìṣẹ́ MBTA ní a ṣe ìdánilẹ́ẹ̀kọ́ fún lórí àwọn ìlànà pàjáwìrì àti ìmúrasílẹ̀. Bí o bá rí ohun kan tí o furasí tàbí o nílò láti jábọ̀ pàjáwìrì kan, jọ̀wọ́ pe: **911** tàbí **Ọlọ́pàá Inú ọkọ̀ ní 617-222-1212,**
**TTY: 617-222-1200**

---

Gbogbo àwọn ìṣe MBTA jẹ́ èyítí kò ní ẹlẹ́yàmẹyà nínú. MBTA ńwà ntẹ̀lé gbogbo àwọn àgbékalẹ̀ ẹ̀tọ́ ará ìlú ti ìjọba àpapọ̀ àti ìpínlẹ̀, èyítí ó ńdènà ìyanisọ́tọ̀ nítorí ẹ̀yà látàrí ìran, àwọ̀, orísun orílẹ̀-èdè, àìkún ojú-ọ̀ṣùwọ̀n ní sísọ èdè Gẹ̀ẹ́sì, àti àwọn áfikún ìwà ìdáàbòbonị mìíran. Fún àlàyé síwájú si tàbí mú ẹ̀sùn wá, jọ̀wọ́ ṣàbẹ̀wò sí **MBTA.com/titlevi** kàn sí wa ní MBTA/MassDOT Ilé-iṣẹ́ ti Onírúurú àti àwọn Ẹ̀tọ́ Ara Ìlú, 10 Park Plaza, Boston, MA 02116, Fóònù: 857-368-8580, tàbí fi imeeli ránṣẹ́ sí wa ní MBTACivilRights@mbta.com